The Chief Secretary to the Government


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. VI. No. 277 SATURDAY, JUNE 2, 1928 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

15 JUN 1928

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi latlai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Eda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silẹ.


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
DrEarlSSloan
SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
mists and Patent Medicine Dealers
Carton adopted 1916.
s for Great Britain
FASSETT & JOHNSON,
Road, London, E.C.
RED ONLY BY
rlSSloan
CORPORATED)
ST. LOUIS. TORONTO, CAN.
ome Office. BOSTON
in United States of America
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Ulcerated Teeth
Stiffness and
Soreness after
Severe Exertion
General Directions
for External Use
Apply Sloan's Liniment freely, rub very lightly
Keep away from
Fire or Flame
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd London.
England

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### KILO TI JẸ?

Lẹnu ọjọ diẹ sẹhin ni a gbọ pe ọkọ wete kan kọja labẹ Kereni Ebute Ero pẹlu ewe, ti ko si si ẹnikẹni ninu rẹ: nigbẹhin-gbẹhin ni a sọ fun ni pe obinrin kan ti o nṣe aya gbẹna-gbẹna kan ati ọmọ rẹ ti nwọn mbẹ ninu ọkọ na ku s'omi; kai, ori ko mọ 'bnsun!!

### EWU MBẸ LỌSAN LORU.

Bi ọmọdekọnrin kekere kan ti nkọja lọ ni lọlọyi lapa ibiti nwọn so agbo kan si ni Isalẹ Eko, bẹni agbo yi kan a lẹju tobẹ ti iho nlanla fi wa ni oju na, iyoku iregbe iṣẹ di iṣẹ gbigbe ọmọ yi digbadigba lọ si ọdọ Dokita kan to mbẹ lapa Ọbun Eko fun titọju.

---

## DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

### ỌLỌRUN GBA NI LỌWỌ IJI-LILE.

Atẹgun oji ti o ja ni idaji owurọ ọjọ Alaruba ọsẹ to kọja, a gbọ wipe o wo igi kan ninu Ọgba Ṣọsi Arọlọya, a si tun gbọ wipe o ri ọkọ meji lọna ọja Agbadayigi, ṣugbọn ako gbọ wipe ẹnikẹni padanu ẹmi Alihamdu li lai.

### INAKI NI' LE ṢITA.

A sọ fun wa wipe nwọn ri Inaki meji ni Agbole Ṣita eyiti nwọn npe ni ile Baba ka, gbogbo awọn ọmọ kekeke ati agba lo nlọ fi ganni wọn, nitori ọpọlọpọ enia ni ko ri ri ti nwọn wulẹ ngbọ wipe Inaki! Inaki!! ẹranko buburu ni.

### ỌLỌLA GOMINA THOMSON.

Ọlọla Gomina Greame Thomson at Aya rẹ lọ si ọdan lọjọ-ọjọ ibi Ọba Victoria, nwọn si ki gbogbo awọn ọmọ ile-iwe patapata lẹhinna nwọn lọ yẹ awọn ọmọ ile-iwe ti Ebute-Mẹta wo ni Ọgba Reluwe.

### GOMINA ATI ỌMỌ ILE-ẸKỌ.

Ọlọla Gomina tẹ iwe kan ni ede Yoruba awọn Tiṣa si pin iwe na fun awọn ọmọ ile-iwe, ohun ti o mbẹ ninu iwe na ni eyi:—

"Oni yi jẹ ọjọ ajọdun gbogbo Orilẹ ede labẹ Ọba kan, a si wa lati fi Ọla si agbajọ Orilẹ-ede Gẹsi han ati lati fi Ọba fun Ọba Alaiyeluwa, ẹniti o jẹ olori agbajọ gbogbo orilẹ-ede na. Orilẹ-ede Gẹsi tobi pupo, ọpọlọpọ onirurnru awọn ilu lo si wa labẹ rẹ; diẹ ninu awọn ilu wọnyi jinna tobẹ to fi le gba eyi ti o yara ju ninu ọkọ Elefi ni ọpọlọpọ ọsẹ ki o to le de inu wọn.

Oriṣiriṣi awọn enia lo wa ninu awọn agbajọ Orilẹ-ede na ti wọn si nsọ oniruru ede, ti aṣa wọn si yato, awọn omiran jẹ Ijoye nla, awọn omiran si jẹ bọrọkinni, awọn omiran ni owo, awọn omiran ni owo, awọn omiran si jẹ talaka. Ṣugbọn bi o ti wu ki wọn talaka to, gbogbo wọn ni ọmọ agbajọ Orilẹ-ede Ijọba Gẹsi. Ati lati fi igberaga yi han ni gbogbo awọn ilu okere ṣe parapọ loni lati ṣe ayajọ yi gẹgẹ bi awa ti nṣe loni. Mo fẹ ki gbogbo yin ni igberaga pe ẹ jẹ ọkan ninu agbajọ Orilẹ-ede labẹ ọba Gẹsi, gẹgẹ bi awọn ilu miran ti nṣe igberaga rẹ, ki ẹ si ma gbiyanju lati yẹra fun ohun ti yio mu y n Ṣ'ai jẹ ọkan ninu Orilẹ-ede na.

Diẹ ninu yin ti gbọ nipa Lord Haig, ẹniti o ku ni nkan oṣu diẹ sẹhin. Lord Haig ni Ọgagun ti agbajọ Orilẹ-ede ni ilu Franse li akoko Ogun Ajakaiye—jagunjagun nla ni. Ṣugbọn ki ṣe jagunjagun nikan ni; nigbati ogun pari, ko joko lati sinmi, ṣugbọn o lo gbogbo ọjọ rẹ toku laiye lati fi han pe o tọ lati mu inu awọn enia to gba ọgbẹ loju ogun ati awọn ti ogun pa enia rẹ dun ati lati tu wọn ninu. Lord Haig gbiyanju lati ran awọn enia miran lọwọ; eyi si jẹ ọkan ninu igi ti a fi nfi oju ẹni titobi wo ninu ilu Gẹsi. Mo ni ireti pe awọn Olukọni yin yio sọrọ nipa rẹ fun yin nitoripe o jẹ enia kan ti a ni lati gbiyanju lati fi ara we.

Bi a ba ṣe eyini, ao fi han pe a ni igberaga pe ọkan ninu agbajọ Orilẹ-ede ni a jẹ nitotọ ati pẹlu

pe a ni ẹtọ pataki lati jẹ ọkan ninu agbajọ Orilẹede na."

## AWỌN ỌMỌ ALIKALI R'OGON NWỌN O R'ỌKUNRIN!

A gbọ wipe onidajọ Ebute-Mẹta kọngọ fun awọn ọmọ Alikali ni kotu oke-ode ni iwọn ọsẹ bi mẹta sẹhin pe ki nwọn lọ san ponw mẹtamẹta ẹnikẹkan pe nwọn huiwa ipata larin ilu ninu ọdun Easter to koja lọ yi, nigbati ọran da bayi boya olukuluku wọn yio lọ ra ewejokojẹ mu ni Ọbun Eko-ẹnikeji!!

## ONI BURẸDI A-RA SANWO.

Ni alẹ ọjọ Satide ijẹjọ ni a gbọ wipe awọn Hausa pẹlu oniburẹdi kan fẹrẹ da rugudu silẹ ni Arọlọya Street (Isale-Agbẹdẹ) a gbọ wipe nwọn lu oniburẹdi na nwọn da ọpọn burẹdi si oju-Gota Ọba nitori burẹdi kọbọ kan, a jiya lori iya Ṣugbọn ohun ti o fa sababi ariwo na ko ye wa arara, nigbati a gbọ wipe awọn ọba yọju si ọran na; *Magana-ya-kare*!

## A-KỌSẸ-KU-ỌLỌRUN TO TO!

Ihin ti a gbọ ni ọjọ Sunday to kọja li eyi pe Ọkunrin kan fi ẹsẹ kọ ni arin ilẹ yi lẹsẹkẹsẹ o si ba bẹ yọ si ọrun ni apandodo; ki lati mọ eyi si, ki Ọlọrun ṣọ ni laiye ti a wa yi.

## GBANJARE O.

Gbanjare awọn ẹniti o nwa ọmọ poju larin ilu lati bi ọjọ mẹta, ohun ti o fa sababi rẹ si ru wa loju pupọ, nitori a ngbọ bi ẹnipe awọn kan wọ'lu nisisiyi ti nwọn nṣọgbọn ji awọn ọmọde gbe lọta lọna ilu o k e r e, nitorina a bẹ awọn Ijọba ki nwọn ba ilu fiye s'ara daradara—Ẹyi ara o!

## ỌGBẸNI T. B. BUKỌ.

A yin si wa leti finrin pe Ọgbẹni Bukọ Akọwe pataki Kotu-Ganran yio gba isinmi oṣu mẹta ni kotu ni ọjọ kini oṣu yi, lẹhin ti isinmi rẹ ba ka 'sẹ yio wa di ẹni ifẹhinti ninu iṣẹ Ọba, alafia ara li ogun ọrọ ki Ọlọrun fi kari kowa,

## ẸJỌ ABUDU WABI ATI TAKUTE.

A gbọ wipe Onidajọ ti bẹ 'gi fun Abudu Wabi Orekan ti Takute mu lẹsẹ ni Ṣọbu awọn oyinbo Alagbọn *Paterson Zochonis & Co*, ti Victoria Road ni lọlọyi pe ki o lọ si ẹwọn oṣu kan, fun ẹsun ti nwọn fi sun. A si gbọ wipe Onidajọ kilọ pe irufẹ Takute baun ko yẹ lati ma dẹ silẹ fun enia nitori ti ẹranko ni nwọn ṣe fun.

## Ẹ KU IPAMỌ O!

A gbọ finrin pe Ọl la Gomina Graeme Thomson, G.C.M.G., K.C.B, yio ba ọkọ "Ajasa" lọ si Victoria, lati ibẹ lọ si ilu Cameroon ati awọn ilu miran larin ọsẹ to mbọ ọjọ kẹsan oṣu yi; yio si tun ba ọkọ "Ajasa" na bọ lọjọ kẹdogun oṣu July to mbọ yi.

## OYINBO ỌGAGUN ROSS.

A gbọ wipe oyinbo Ọgagun W. A. Ross, C.M.G., (*Senior Resident of Oyo*) ẹniti a gbọ wipe o gba Oloye Obanikoro ati isangbe rẹ ni imọran ọyọ ti nwọn lọ ninu oṣu May to lọ yi, lọ si ilu oyinbo ni ọjọ kejidinlogun oṣu *May* to pari.

## PIRIFI-KANSULU.

A gbọ wipe Ilu oyinbo (*Privy Council*) ti ni ọjọ kẹdọgbọn oṣu May to pari yi, fun isinmi, a si ni itanma pe nwọn yio tun ṣi titi ọjọ karun oṣu yi tabi titi ọjọ mẹta.

## LASIGBO AIYE!

Aba Sule Balogun yọ gidigidi a yọ ọ fun 'ra wa fun orire ni ti awo ti a gbọ wipe o ṣe lọjọ Monday ọsẹ yi fun dida silẹ ti a gbọ wipe Kotu da silẹ latari ẹjọ Olemọ ti nṣiṣẹ fun awọn Oyinbo-Oniṣowo (G. B. Ollivant) eyiti nwọn ti mbẹ lẹnu rẹ lati ojo melo sẹhin-Ki Olodumare fi mọ bayi o, a si ki gbogbo ẹbi ọrẹ aya ati ojulumọ patapata nwọn ku orire!

## EIDIL-AZUA.

Ni dede agogo mejọ ijẹrin Wednesday awọn Jama-ilu ba Lemọmu Ligali lọ kirun "Eidil-Azua" eyiti a mọ ni Iru ọdun Ileya; lẹhinna gbogbo awọn Imale iyoku pa lọ kirun ni ipo ti olukuluku wọn wa, bi ọdun na ti to bi ti o ladun to, sibẹsibẹ ko dabi alara fun awọn Ilu, eyiyi fihan wipe inu ko dun to bẹ, ekini ko si owo, ekeji ko si iṣẹ ẹkẹta ni olubori ko si alafia ni ilu; nitorina a bẹ Ọlọrun Olodumare ki o ma ṣai jẹki ipẹhinda ọdun awọn Imale sọ ilu di rere nipa idunnu ati ayẹ larin ijọ pẹlu.

A ki gbogbo Musulumi patapata nwọn ku ọdun nwọn ku iyedun a ṣe ṣ'ẹmi o.

## AYAJỌ ỌJỌ-IBI ỌBA.

Ni ọjọ *Monday* ọtunla ti o nṣe ojọ kẹrin oṣu yi ni ọjọ-ibi Ọba Alaiyeluwa Iku Baba-yeye Alaṣẹ ekeji Oriṣa (King George) pe lati ṣe gẹgẹ bi atẹhinwa: gẹgẹ bi ọmọ abẹṣẹ rẹ, ki yio si iṣẹ fun ẹnikẹni lọjọ na. *God save the King.*

## ẸBGẸ JANMA ANSARUD-DEEN KEKERE.

Ere Cinematograph Alarakuyamu kan mbẹ fun awọn Ẹgbẹ yi loni Satide ni ile Afariogun (Glover Memorial Hall,) ni iwọn agogo mẹjọ alẹ —ṣibaṣiba ni ẹsẹ awọn Saraki yio pe sibẹ, awọn Lọya diẹ yio si lọ si ibi ere na, o tọ wipe ki ki ẹ lọ fi onjẹ oju fun oju, fun iranlọwọ pataki nipa inawo ile-Ẹkọ ti awọn Ẹgbẹ yi ndaba lati ṣe.

## ORI III.

## IWA—ẸGBẸ KIKO ATI APẸRẸ.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KỌKANLA.

Awọn ẹni nla ti mu ki awọn Ọba ilu (Kings and Emperors) ati awọn olori alufa giga (Popes) gba fun wọn. Francis de Medicis ko jẹ de fila bi o ba gba Michael Angelo sọrọ, Julius iii a si jẹ ki o ojoko ti on nibiti awọn agba alufa bi mejila wa ni iduro. Charles v yẹ si apakan ki titian kọja. : bẹna ni, ni ọjọ kan ti gege onirun yẹtu-yẹtu ti onişọna-awọran yi (*titian*) nlo bọ lọwọ rẹ, Charles (Ọba) bẹrẹ mu fun, o ni, "Tirẹ to ki Ọba ma sin ọ" Les x ni ọjọ yio yọ oluwarẹ ni ijọ ti o ba tẹ iwe orin ti Ariosto şe ti o ba si ntı wọn, aiyaşebi okọwe-orin na ba fun oluwarẹ ni aşẹ.

Olori alufa giga yi kanna ni o lọ ki Raphael nigbati o nku lọ, bakanna bi Francis I. ti lọ ki Leonardo da Vinci.

Loto ni Haydn fi ẹsọ yan, nigbati o nsọrọ nijọ kan, pe gbogbo enia ni o fẹran on afi awọn ọga eleto orin-duru, şugbọn gbogbo awọn ijimi eleto orin-duru ni ki isọsẹ ki nwọn to gba fun ara wọn,

Loju wa Haydn papa ki işe onilara enia. O gba fun Porpora, ẹniti okiki rẹ kan pupọ, tobẹ ti o fi pinu lati lọ si ile rẹ lo wọ işẹ bi iriju ọmọ-ọdọ lẹhin ti o fi wa ọna ti o mọ oju awọn ẹniti Porpora nba gbe tan, nwọn gba si işẹ na, Ni kutukutu hai lojojumọ, a gbọn ẹwu ọgbẹni rẹ pẹpẹ, a dan bata rẹ, a si tun fila-irun rẹ ti o ti gbo şe. Ni akoko Porpora a kanra mọ alatojubọ yi, şugbọn kẹrẹ-kẹrẹ o ye kanra mọ, o si wa fẹran rẹ. Ko pẹ ki o to ri oye ẹbun bi iriju ọmọ-ọdọ rẹ ni, o si pẹ, o dari ẹbun ti o ni yi si ọna ti Haydn fi di okan lẹhin na.

Haydn papa fi tọkan-tọkan gba fun Handel. Ni ọjọ kan o sọ pe, "on ni baba gbogbo wa." Scarlatti gba fun Handel, a si ma ba kakiri Italy, bi o ba si gbọ ti ẹnikan darukọ rẹ, on a sa ara rẹ ni ami agbelebu gẹgẹ bi apẹrẹ ọwo ti a ma nbu fun Ẹni mimọ.

Bakanna ni Mozart gba fun, o ni bi o ba wu Handel a tẹ duru bi igbati mọnamọna kọ. Beethoven juba rẹ o pe ni "Ọba eleto orin,"

Nigbati Beethoven nku lọ ọkan ninu awọn ọrẹ rẹ fi ogoji iwe eto orin Handel ta lọrẹ. Nwọn ko awọn iwe na wa si iyara rẹ, o şe giri, o tẹjumọ awọn iwe na o nwo wọn, o wa nọwọ si wọn o ke o ni "Wo—nibẹ ni otọ gbe wa!"

Ki şe kiki awọn oni-mimọ ti o ti kı nikan ni Haydn gba fun, o gba fun awọn şaşa wẹrẹ ti o wa ni igba rẹ pẹlu, Mozart ati Beethoven.

Awọn ti ko to enia le ma şe ilara awọn ẹlẹgbẹ wọn, şugbọn awọn ti o ba to enia, awọn ẹni nla tabi ẹni rere şan, a ma wa ara wọn kan, nwọn a si ni ifẹ ara wọn.

Ohun ti Haydn kọ nipa Mozart ni eyi :—

"Iba dun mọ mi bi o şe pe emi le mu gbogbo awọn ẹniti o fẹran eto-orin, papa awọn ẹni nla mọ riri, ki nwọn si gba bi emi ti gba pe eto-orin Mozart ko lẹgbẹ. Nigbana ni gbogbo awọn orilẹ-ede yio ma ba ara wọn du. Olukuluku ilu a fẹ ki ari awọn ni o ni ohun iyebiye yi. Kiki pe ki ilu Prague sa agbara ki o ma bọ lọwọ wọn ko to; o tọ ki awọn ma san owo fun pẹlu; bi eyi ko ba si nibẹ adun kan ko si ninu itan igbesi aiye ẹniti o jẹ pe nipa imọ tabi ọgbọn-ori ni o fi di ẹni nla.

Inu bi mi ngbati mo ro titi pe bi o ti jẹ ko si iru Mozart, sibẹ a ko i ti ri Ọba ilu kan ti yio gba ti yio ma san owo, fun. Ẹ fi ori jimi ti mo ba fi igbona ara sọrọ; mo fẹran ọkunrin na pupọ."

Bakanna ni Mozart fi tọkan-tọkan gba fun Haydn. O sọ fun oni-rena kan ti o nsọrọ Haydn pe:

"Ọgbẹni, bi a fọ emi pẹlu rẹ pọ şe ọkan, a ko to şe Haydn kanşoşo."

Bẹna ni nigbati Mozart kọkọ gbọ işe-ọwọ tẹ duru Beethoven, o ni:

"Gbọ bi ọdọmọkunrin ni ti ntẹ duru; gba eyiti ngo sọ fun ọ yi, o mbọ wa di ẹni nla"

Buffon gba fun Newton pe on ni o ju gbogbo awọn ọlọgbọn (*Philosopers*) lọ tobẹ ti ki işai gbe aworan rẹ kalẹ nigbati o ba nşişẹ.

Bakanna ni Schillea si Shakspeare, o si iye ọdun ti o fi tọwọ-tọwọ ati tara-tara kọ iwe shaspeare titi on na fi di ẹniti ndamọ fun ara rẹ, nigbana ni o tubọ gba fun ju ti akọkọ lọ.

Pitt ni ẹniti Canning mu ni ọga ti o si jẹ akọni rẹ, on ni o nfi ara we ti o si nfi ifẹ gba fun Canniug ni:

"Ẹnikan ni, nigbati o wa laye, mo fi ọkan ati ẹmi mi gbogbo sin. Nigbati Pitt fi ku emi ko mọ ẹnikan ni aşiwaju mi; gbogbo ibi ti enia ma ju lọna ti işẹ oşelu, mo ti ko temi sinu iboji rẹ."

Ni ọjọ kan bi Ọgbẹni Roux (*French Physiologist*) ti nkọ awọn ti o nkọ ẹko lọdọ rẹ, lọwọ ni Sir Charles Bell, ẹniti awọn ilu okere mọ riri rẹ, nipa işẹ wiwadi awọn ohun ijinlẹ, ju bi ilu rẹ ti mọ riri rẹ lọ, wọle. Bi olukọ yi ti ri pe on ni, o dawọ ẹkọ ti o nkọ wọn duro, o ni:

"Ẹnyin arabi, iba eyi ti a şe yi to niti oni, Sir Charles Bell ni ẹ fi oju kan yi!"

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

## DOSUNMU A.D. 1853–1885.

*Copied from Losi's History of Lagos*

By Kekere-Awo

To the Editor "Eko Akete"

King Dosunmu was placed on the throne of Lagos on the 22nd of June 1853, he received the support of the English Government.

One day during month of March 1854, King Dosunmu left home to offer sacrifice to the god *Erinkinran* at the village Okepa, he went with his attendants and some of his wives; after he had left his countriers began to clean the palace "Iga Ibunganran" in order that when the King arrived in the evening he might find everything neat and tidy, they took all the furnitures and petty things out of the house; swept the whole and put them back to their proper places but they forget outside casks containing Gunpowder (Ẹtu-ibọn) which according to custom were generally stored inside the palace unlike the Europeans.

When it was dusk they remembered that the kegs of the Gun-powder were still left outside, and at once they began to remove them into the house, as the kegs were being rolled into the house a lot of powder fell out of one of them without being perceived by any one.

At the evening time a man named Ọdẹ whose duty it was to light the lamps in the Court threw by accident a match on the ground and it set fire to the powder on the floor, which rang along until it came to the kegs in the store,. all the kegs took fire blew up, and there was a terrible shock, by this time King Dosunmu had not returned from Okepa, but when he was coming home in his paddle canoe, some of his sons hastened to inform him the great aceident during his absence, then the canoe-men proceeded to row with great joy and were singing homeward the following songs :—

1. Isẹlẹ to sẹ ko ba Akamọ n' le
2. Aseba ki ba agbe
3. Aseba ki ba aluko
4. Ẹtu to gbina ko ba Akamọ n' le.

On the 2nd of August 1854, a big Leopard entered the town of Lugos and cause many injuries, the Leopard nearly killed two men by infilicting wounds upon them, the Leopard was at last killed by Diviner (Babalawo) from the interior.

A few days after this occurrence, a deer also gained entrance into the town and was killed by the people, the 15th of April 1856, witnessed the explusion of Madam Tinubu from Lagos by King Dosunmu.

The cause was this, Madam Tinubu was very rich, her wealth was so great that she hardly knew the number of her slaves. As there is scarcely anything a rich person connot do, she would take upon herself responsibility of issuing orders which should come only from the King; she was a friend of the King of Dahomey, and anything that occured in Lagos was secretly reported by her to that King.

When King Dosunmu tired of her conduct he complained about her to consul B. Cambell, and received authority to banish her from the town. the consul even supplied the King with policemen to assist him in driving out of the woman.

King Dosunmu accordingly sent her an order to leave the town at once, and not to pass another evening in the town, but that should sleep in her farm-house at Igbobi; But Tinubu came to the King at his palace began to relate to him, the story as to how she and King's father (Akitoye) had been on very friendly terms which fact he himself was aware of; but the King informed her that he did not want her to live any more in the town and more also he did not like her to sleep in Lagos that night,

When she returned home, her slaves were prepared to fight, the policemen, but she informed them that she was not a slave of Abeokuta, but a free born, and she had walked to Lagos and that God blessed her; she said that she and her slaves shoulk not fight, but that she was willing to leave Lagos—in this way Madam Tinubu left Lagos that day.

On the 6th of August 1861, a public declaration was made that the country was ceded to the English Government, this declaration was confirmed by King Dosunmu himself who signed the document in the afternoon at his square in the following terms :—

1. In order that the Queen of England may be the better enable to assist, defend and protect the inhabitants of Lagos, and to put an end to the slave trade in this and the neighbouring countries and to prevent the destructive wars so frequently undertaken by Dahomey and others for the capture of Slaves, I Docemo do with the consent and advice of my council, give transfer and by these presents grant and conform unto the Queen of Great Britain, her hiers and successors for ever, the port and island of Lagos, with all the rights profits, territories and appurtenances whatsoever thereunto belonging and as well as the profit and revenue as the direct, full and absolute dominions and sovereignty of tne said port, island and

premises, with all the royalties thereof, freely, fully, entirely and absolutely. I do also covenant and grant that the quiet and peaceful possession thereof shall, with all possible speed, be freely and effectually delivered to the Qeen of Great Britain or such persons as Her Majesty shall appoint for her use in performances of this grant; the inhabitants of the said island and territories, as the Queen's subject and under her sovereignty, crown, jurisdiction and Government, being still suffered to live there.

2. Docema will be allowed the use of the title "King" in its usual African signification, and will be permitted to decide disputes between native of Lagos with their consent, subject to appeal to British laws.

3. In the transfer of land, the stamp of Docemo affixed to the document will be proof that there are no native claims upon it and for this purpose he will be permitted to use it as hitherto. In consideration of the cession as before mentioned of the port and island and territories of Lagos, the representatives of the Queen of Great Britain do promise subject to the approval of Her Majesty, that Docemo shall receive an annual pension from the Queen of Great Britain, equal to that net revenue hitherto annually received by him; such pension to be paid at such periods and such a mode as may hereafter be determined.

Their Marks x Docemo
x Telake
x Rocamena
x Obalekow
x Acheboug

Noman B. Bedingfield, Her Majesty's ship "prometheous."

Senior officer, Bights Division W. McCoskry, Acting Consul.

Lagos, August 6, 1861.

(*To be continued*).

---

## NWỌN NGE NYIN LỌWỌ, Ẹ NBỌ ORUKA.

### APA KEJI.

Lode ti oni ko si ohun meji ti ẹlomiran tabi pupọ Ọmọ Eko tabi alejo omiran nfẹ lati ma fẹ ṣe gbajumọ ni ilu yi bibẹkọ iwa agbere ati pamṣakuta bi ọdọmọde kunrin omiran ba ṣẹṣẹ balaga ti ko ba yi ti suu mọ obinrin koi ti ṣe gbajumọ, tabi bi ọdọmọde binrin miran ba ṣẹṣẹ nri nkan ọmọbinrin rẹ, tabi ti o ṣẹṣẹ npa koko'yan eyiti o ma nyun wọn loju ganran-ganran, bi nwọn ko ba yi ti nlemu ọkunrin kiri bi ẹja epiya, ara koi ti rọ wọn, nwọn koi ti di gbajumọ, nwọn si sọ ohun buruku yi di ohun ayọ fun wọn ti o jẹ wipe bi wọn ba ji ni kutu owurọ ọjọ kan, bi nwọn ko ba yi ti huwa aidara wọnyi, yio jẹ ohun ailera fun wọn tobẹ gẹ ti o mu ọpọlọpọ ọmọge tabi ọpọlọpọ awọn ọmọkunrin wọnyi nṣe aigbọran si awọn obi wọn, nipa pe ki obi ẹlomiran sọ fun wipe iwọ ọmọde yi, o ko gbọdọ jade lọ si ibẹ nyẹn tabi o ko gbọdọ gba iye asiko bayi ni ibiti o nlọ tabi nibiti mo gbe ran ọ, ti nwọn si ma ṣe aigbọran si ẹṣu ti nwọn si ma ṣe eti gbọnin si ẹbọ, eyi yi ni pe ti nwọn ma ṣe eti kunkun si ikilọ awọn obi wọn, nitori kini nitori iwa agbere ati pamṣaga.

Nigbati awọn obi wọn ba nṣe ikilọ fun wọn nigbana ni nwọn tubọ ma joye agbe'gboro-dagba ani iwa ipata ti o nfa oṣi ba wọn.

Ani bi nwọn ba ji ni kutu hai owurọ ọjọ kan, ti omiran ko ba yi ti lọ huwa jagbajagba, aisan ti o mba wọn ja koi ti le fuyẹ, bayi ni wọn sọ iwa agbere yi di onjẹ, ani iwa "tanimamumi" aja wi're wọnin! aja o wi're wọnin! iya ati baba to bi wọn ko to ilọ ki fun wọn, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti awọn alarõ kan mọ, awọn wundia nrin arin ṣẹpa kiri awọn adelebọ nrin arin wọdi kakiri igboro ilu.

Bi nwọn ba kọkọ fẹ bẹrẹ lati gbe iṣẹ oṣi ati arede yi da ni, nwọn a lọ si ọdọ awọn Alagbẹdẹ pe ki nwọn ṣe yeri ti a le fi ṣe ẹgba ọwọ ọmọde, lati fi si eti, lẹhinna, nwọn a ma lọ si ile-iṣẹ awọn Dokita, nwọn a ma lọ tọrọ ẹfẹ-owu lati ma fi bọ eti pẹlu, lẹhinna nwọn a lọ ra apamọ-Oyinbo tabi ti Inago nwọn a ma ya Ṣabu kiri lati le gbe wọn ni agbeda, nwọn a ma fọ gbogbo ilu kiri rai, Ọlọrun kuku ṣe nwọn o tilẹ ri kọbọ gba mọ, awọn Lọya ti nwọn nkigbe, ngbọ ẹnikan ri oju ẹnikan mọ loni—Loya omiran to jẹ wipe o di oṣu kan ti o ti nri iṣẹ ṣe lo ma sọ wipe on yio ri owo kan ko fun wọn, agbare-gbabọ, ao gbọ wipe omiran ku lojiji, ngbọ ki nwọn to ṣe ti aja ki nwọn to ṣe ti ẹran, nibiti awọn Adelamu pẹlu Kunakuna gbe wa.

Ọpọlọpọ ọkunrin lo ti nda ile haya sode fun ale lati ma ṣe agbere, ọpọlọpọ irufẹ awọn ẹni nwọn ko ha ti sọ arawọn di olori-buruku loni ? ! !

(*Koi pari*).

ỌMỌ-ILU.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, JUNE 2, 1928.

## "A Ṣ'ỌGBỌN P'AGUNTAN JẸ ILA, O NI OJU AGUNTAN MBA ON LẸRU."—( Owe ni o" )

Owe ti a ko bojuwẹhin lati pa fun Ijọba leyi nigbati a gbọ ti alai fun Ile-iwe kankan ni owo lọdunni fun onjẹ ti a ma nsaba se fun wọn lọdọdun ni akoko *Empire Day* tabi iranti ayajọ ọjọ ibi Ọba Queen Victoria Ologbe: nigbati a fimu finlẹ lati mọ kilo mu Ijọba ṣe bayi, a sọ fun ni pe awọn Ijọba gbọ pe nigbati nwọn ba fun awọn Olotu Ile-iwe kan lowo lati se onjẹ ọdọdun ti a nsọrọ rẹ yi a sọ pe nigba miran onjẹ ti nwọn nse fun awọn ọmọde na ki dara to, ati pe o si ni iye igba ti awọn olori ṣukuru miran nse bọ wọwọ fun awọn majeṣi wọnyi jẹ lọna bayi; a sọ pe mu-ṣiṣu gburu ati aisan miran ki ye ba awọn ọmọ ile-iwe wọnyi ja lẹhin ọjọ diẹ ti nwọn ba ti jẹ irufẹ onjẹ bẹ tan; a si tun gbọ pe owo ti Ijọba nfun ṣukuru kọkan ki de ibikan rara lati fi se onjẹ to kayin fun awọn ọmọ ile-iwe wọnyi ati pe o ni'ye igba ti awọn olori ṣukuru miran tun nmowo lati inu apo wọn jade lati fi kun owo diẹ ti Ijọba fi ju ṣukuru miran lori. Bayi ni a gbọ ọrọ na si.

Ni tiwa ko yẹ ki Ijọba hawọ owo ọdọdun yi ni fifi fun Ile-iwe kọkan gẹgẹbi nwọn ti nṣe lati ẹhin wa: Họwu, Ijọba le fun ṣukuru kan ti o ni bi irinwo ọmọ ni pọun mẹwa ( £10 ) ki irufẹ owo bẹ ta Ijọba lọsi? Ohun ti o jẹ pe ọdọdun ni o nṣe bẹ, ṣugbọn ti o ba di pe ki Ijọba ma fi ọgọrọ Oyinbo ṣe Alabojuto Ẹkọ ( *Superintendents of Education* ) pẹlu owo ribiribi nkan bi £400 titi de £500 lọdun ni sisan fun wọn, owo yio wa lati ma ko irufẹ awọn Oyinbo bẹ wa. A ko wijọ si eyi tobẹ ṣugbọn ohun ti a nsọ nipe ko ye ki Ijọba nipa ọwọ hiha wọn da ẹgbagbeje ọmọ ṣukuru loro onjẹ ọdọdun ti nwọn ti nireti lati ma jẹ ni igba *Empire Day*, ọjọ ti pupọ enia mọ si ọdun awọn ewe, elo la m'okun Wundia ti Adelebọ nrin arinwọdi, elo ni Ijọba iba ma na lọdun fun irufẹ onjẹ bayi ti yio mu apo wọn gbẹ: kaka ki nwọn se eyi a gbọ pe nṣe ni nwọn ṣa awọn ṣukuru diẹ lati lọ mu wọn wo awọn Ile-iṣẹ ni Apapa. Kini ọmọde mọ nipa eyi, nigbati o jẹ pe lati igbati a ti da pe ki awọn ọmọ ile-iwe ma to lọ si ọdan, ki nwọn si ṣere idaraya, ki nwọn si "mi eyọ" nijọ keji, njẹ ọgbọn ko s'owo ko s'owo ti Ijọba ngbọn yi ki yio jẹ ki onjẹ fifun awọn ọmọ ile-iwe wọnyi wọlẹ nigbẹhin gbẹhin?

A ke si awọn Igbimọ Ẹkọ ( *Board of Education* ) papa a ke si awọn Enia Dudu bi awon ti a ti igbe sipo giga nibẹ ki nwọn maṣai da ọrọ ti alaifun awọn Ile-iwe lowo lati se onjẹ lọdunni ro; ki iṣe wipe bi nwọn ko ba jẹ onjẹ na mọ, ebi le ri wọn gbe ṣe, ṣugbọn nigbati a ba niran titori tani a nṣe iranti *Empire Day* ati bi o ti fẹran awọn ewe si nigba aiye rẹ, o yẹ gidi-gidi ki Ijọba ya owo kan sọtọ fun irufẹ ariya onjẹ bẹ; ki nwọn si mọ pe ẹyin lo ndi akukọ, ati pe a ko mọ ibiti ori nbẹṣẹ re,

Agba bura b'ewe ko ṣe ọ ri !!!

## "VOTE FOR ME" TABI D'IBO FUN MI.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU. ]

Mo bẹrẹ f'oji,

Vote for me, Vote for me, tabi Dibo fun mi, Dibo fun mi jẹ ede ti a nsaba ma ngbọ l'akoko Idibo ti a yan enia gẹgẹ bi Aṣoju ilu lọ si Igbimọ Aṣofin ( Legislative Council ) tabi Igbimọ ti Munisipa ( Municipal Council ) nibiti nwọn nro ẹjọ Tanwiji ati yanmuyanmu.

Ṣugbọn kini itumọ Vote for me? O daju pe ọpọlọpọ enia ni yio wipe ko ni itumọ meji ju "Dibo fun mi" lọ. Bẹni. Ṣugbọn kilo njẹ "Dibo fun mi" papa, tabi bawo ni Ilu ti ṣe le dibo fun enia, nigbati Ilu ko nṣe Babalawo; ṣe ẹnikẹni to ba fẹ lati dibo ni lati tọ Baba Onifa tabi Alagbigba lọ lati lọ dibo lọdọ wọn, lati lọ wọ

...han, tabi lati lọ "Ilu sabi lodọ Afa," bi o si şe ...ope oko aje ni oluwarę fę lati lọ ni, şe yio lọ si ...dọ Baba alaje lati lọ mu aje, tabi ki o lọ dibo aje ...odọ Ologbe Tairu alaje l'ọna ọrun lọhun.

Nję kini ituọm pataki ti a le fuu Vote for me ...inọşe "Jọwọ, gbe ẹru Ilu ru mi" Ęru nla ni ...ẹru Ilu, ẹru ti enia ko ba şọra gidigidi, ti o le ru ...ni aruyọke ni; ẹniti o nkigbe pe Vote for me, ...Vote for me, o nbẹbẹ pe ki a di ẹru Ilu le on lori ...ẹniti o ba si nbẹ iru ẹbẹ ifẹ bẹ, ẹbẹ ifiara ẹni ...bọ, o ni lati jẹ akọni enia, ti ọgbọn ati lakaye ...pe şanşan, ti o si ti mura tan lati "fi ohun ...ọgbo ti o ndun makwnnu han awọn alagbara, ...lati jẹ alagbawi awọn Odi"

Bi igbati a gbe gari ẹşin silẹ ti ewurẹ yọ'ju, ...ẹni ẹlomiran ri ninu awọn to ti daba lati gbe ẹru ...ru ni ọdun melo kan sẹhin ki wọn to bo'lẹ ...papira. Ẹlomiran wa ninu wọn ti a le wipe o ...ga to Erin, ti gannọku ẹhin rẹ si to ti Ẹfọn, şugbọn kini komi ẹni bẹ, bi ilu ko ba fẹ ẹ..

Ẹlomiran, ẹwẹ, o wa ninu wọn ti a le di ẹru Ilu ...ru bi aye ba wa, tabi ti o ba kesi awọn ẹni ti o wa ...si idi ẹru papa lati gbe ru on. Şugbọn iregbe ...asan ni eyi, o ti bọ lọwọ oşu, o di arọn-mọju.

Ki a m'ẹnu kuro patapata ninu gbogbo "Idibo" ...ti o ti kọja ati gbogbo awọn to şe wahala lasan ti ...awọn ko si ri ọna gba wọ Ile kuro, ki a le ri aye ...sọrọ lori awọn to ni anfani lati de Igbimọ gẹgẹ bi Aşoju Ilu.

Ki a to bẹrẹsi aşaro wa lori wọn, a kọkọ fẹ lati ...sọ pe, a ko ba ẹnikẹni to ba tumọ Vote for me ni "Dibo fun mi" wi rara, nitoripe lẹhin ti olukuluku ẹniti o le dibo ba dibo ni aşiri tan, ẹniti ibo ...enia pupọ ba mu, ni ao di ẹru Ilu ru ni Igbimọ Aşofin. nitorina bi a ba tilẹ le tumọ Vote for me si "Dibo fuu mi" ko buru; şugbọn yio dara-jnlọ ti a ba le tumọ rẹ si pe "Dibo fun mi ki gbe ilu ru" tabi "Jọwọ, gbe ẹru Ilu ru mi."

Itumọ ki tumọ to wu ki ẹnikẹni le fun ọrọ na, ẹyiti a fẹ ki o ye onile ati alejo, awo ati ọgbẹri yekeyeke nibẹ ni pe, Ẹru Ilu ni awọn Aşoju wa nbẹbẹ lati gbe ka ori nwọn nigbati nwọn nke si ọ, ti nwọn nke si mi pe, "Dibo fun mi, Dibo fun mi"!

Jesu tabi Anọbi Isa ni a gbọ pe o ni "Ki nşe gbogbo ẹniti o npe On ni Oluwa, Oluwa, ni yio de Ijọba ọrun." Bẹ gẹgẹ ni ko nşe gbogbo ẹniti o nbẹbẹ lati gbe ẹru Ilu ru nitoripe bi oniruru Alaru to nru ẹru aşọ ati ẹru nkan miran ti wa, bẹni oniruru ati oniwaiwa Alaru miran wa to nja ijakadi lati ru ẹru Ilu, nitorina ni Ilu şe ni lati şọra gidigidi nipasẹ iru enia ti Alaru rẹ jẹ, tabi ti Alaru rẹ yio jẹ.

Talo ha jẹ fi ẹru ara rẹ şe fun Alaru ti ko lagbara to, tabi adagbamadanu Alaru, talo ha jẹ fi ẹru ara rẹ şe aru fun "ọmọ Jaguda," tabi enia kenia ti ẹnikẹni ko le fi inu tan; ani talo ha jẹ fi ẹru rẹ şe fun Ẹlẹkẹ ebu, ati a bu ni bi ẹ ni la'yin, tabi Alaru ti yio ma ja kita kita şa fun ire ara ode laibikita rara fun ẹniti o fi ẹru şe fun un..

Nję bi olukuluku enia ba ni lati şọra gidigidi bayi lati mọ iru enia ti o yẹ lati fi ẹru şe aru fun, melo melo lo yẹ ki gbogbo Ilu şọra gidigidi lati yan ẹniti o to lati fi ẹru Ilu şe fun, ninu ọpọlọpọ, ninu to mu orukọ dani lati ru u.

Alaru ti ko lagbara to pẹlu Aşoju ti iwe ati gẹsi rẹ ko da loju daradara, ẹgbẹra ni nwọn. Ẹlẹrẹkẹ ebu Alaru pẹlu Aşoju ti yio ma bu ilu şakaşaka, ọkana ni awọn mejeji.

Aşoju ti yio ma ji ọrọ Ilu lọ sọ fun Ijọba kẹlẹkẹlẹ laşiri pẹlu ọmọ Jaguda, t'ẹgbọn t'aburo ni nwọn; bẹni ko si iyatọ kan larin Aşoju ti yio ma şe atilẹhin fun Ijọba şa lori ofinkofin, yala o dara tabi ko dara, pẹlu Alaru to şe pe ire ara ode nikan şa lo nwa laibikita fun ẹniti o fi ẹru şe fun, odo kanna ni awọn mejeji nda ọra si.

Şugbọn ati Alaru daradara ati buruku to nru ẹru, ewo lo nru ẹru ọfẹ ti ki ngba owo ninu awọn mejeji? Ko si; işẹ owo ni gbogbo wọn njumọ nşe pọ; şugbọn ẹru Ilu to wuwo wuwo pupọ ju ẹru igi tabi ẹru obi, ti aşọ, oko ati ekuro ti Alaru nru, ti awọn Aşoju wa ni Igbimọ Aşofin Ilu ati Igbimọ Munisipa nru nkọ? Elo ni awọn ngba lọwọ Ilu tabi lọwọ Ijọba?

Ani, a tun bere pe ẹru nlala, ẹru Ilu ti awọn Aşoju wa nru nkọ, elo ni nwọn ngba? Ha? Wọn ko gb'owo, wọn ko gb'obi lọwọ ẹnikẹni, kaka bẹ ebu ha kọ ni nwọn nri gba l'ọtun l'ọsi lai sọ ti iregun ti a nşe fun ẹlomiran ninu wọn pe awa la sọ nwọn di "Ọlọla."

O ni iye ti gbogbo awọn Aşoju to wa ni Igbimọ ilu Oyinbo (Parliament) ngba lọdọdun lọwọ Ijọba ati lọwọ Ẹgbẹ ti olukuluku wọn wa, o si ni ọwọ ti Ijọba papa nbu fun ni Igbimọ na, ki a ma şẹşẹ sọ ti ara itu; o ni iranlọwọ ti ara Ilu nşe fun wọn nipasẹ fifi ọkan tan wọn, ati jijẹ ki nwọn mọ bi nkan gbogbo ti nlọ si ni Ilu.

Şugbọn ni ilẹ yi nkọ, awọn Aşoju wa ni lati şe wahala fun ra wọn pupọ lati le mọ bi nkan ti nlọ si jakejado ilu Nigeria, bi o ti nlọ si nibi işẹ Ọba, ati bi nkan ti nlọ si ni ilu Oyinbo papa, ki nwọn to le ri ohun duro le lori sọrọ ni igbimọ; anu si şe wa pupọ lati ri i pe iranlọwọ (a ko wipe iranlọwọ owo o, nitoripe ọfẹ patapata ni nwọn nşe işẹ wọn bi Aşoju), ani anu şe wa lati ri i pe iranlọwọ ti ti nwọn nri gba lọwọ Ilu ko to nkan, ọpọlọpọ işẹ ati ọpọlọpọ wahala "Baba Isalẹ." The Honourable the whispering Member for Lagos.

Ẹlomiran ro pe ti a ba ti ni Aşoju to nşe işẹ Dokita ninu Igbimọ Aşofin tabi ti Munisipa, bi ara ẹnikan ko ba da, Dokita Aşoju yi ni lati tọju oluwarẹ l'ọfẹ; bi o si şe Lọya ni, o ni lati ma şe

iṣẹ ọfẹ fun ilu; ti o ba si jẹ pe Wọnlẹwonlẹ ni, ko ni lati gb'owo ilẹ ti o wọn, nitoripe Ilu lo dibo fun wọn ki wọn to di Aṣoju ni Igbimọ. Eyi ko nṣe ero to tọ suna rara, a si dupẹ pe enia diẹ kiun ni iru ero bẹ wa lọkan wọn. Inu wa yio si dun bi iru ero bayi ba le kuro lọkan olukuluku enia.

Dajudaju a ko le ṣe ọmọ awo bi ao ti ṣe ọmọ ọgbẹri, nitorina o da wa loju gbangba pe bi gbangba pe bi ohunkohun ba wa ti ẹnikan ninu awọn Aṣoju wa le ṣe fun ojulumọ enia lọfẹ, tayọtayọ ni nwọn o fi ṣe e; ti o ba si ṣe iṣẹ ti nwọn le gba nkan bi pọun mẹwa ṣile mẹwa lọwọ "ara ile," boya nwọn le gba pọnwun marun ṣile marun lọwọ "ara ile," ki nṣe pe ki gbogbo rẹ kuku jẹ ọfẹ bi ẹlomiran ti nro,

Ṣugbọn iṣẹ ti o ba kan alafia tabi inira gbogbo Ilu, tabi ti ọpọlọpọ enia ni Ilu, lọgan ni nwọn o dide si i gẹgẹ bi nwọnọti nṣe lati ẹhin wa lai gba kọbọ kan ṣoṣo pere lọwọ ẹnikẹni.

Ẹru nla ni Ilu di ru awọn Aṣoju mẹfẹfa ti a yan si Igbimọ Aṣelu ati Igbimọ Munisipa, adura wa si ni pe ki Oluwa ba wọn gbe ẹru na ni agbe yọ'ri; bi ẹfufu tilẹ nja, ti igba nle, ki wọn ṣa le ni iṣẹgun ni adura ti wa, ki eti Ijọba si la si ohun ti nwọn nba sọ ọ, nipa ire ati alafia Ilu. Ki Ijọba maṣe jẹ ọlọrun wiwaki ati eleti kunkun.

Ọrọ ti a ba sọ fun ọgbọ ni ọgbọ ngbọ, ọrọ ti a ba sọ fun ọgba ni ọgba ngba, ṣiṣẹ ṣiṣẹ ni ti ilakọṣẹ, Aṣẹ.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### Miss Ibironke Macauly.

The many friends, families, admirers and Patients of Dr. M. R. L. Macaualay, M.B., CH.B. L.M., of 17 Victoria Road, Lagos, will join in congratulating him on the success achieved by his daughter Miss Ibironke Macaulay who has recently passed the Central Midwife's Board examination in England.

### Mr. T. B. Buko, Assistant Chief Registrar.

Mr. Thomas Bankole Buko, Assistant Chief Registrar of the Supreme Court of Nigeria, proceeded on three months' leave of absence as from the 1st June, 1928, after the expiration of which it is understood he will retire on pension after 40 years' faithful and meritorious service. Mr. Buko had served in several offices like His Majesty the Customs Department, Attorney General's office and the Secretariat. Arrangement has been made, we learn, to transfer Mr. J. H. Smith, Registrar, Majistracy, Lagos, to the Supreme Court to succeed the former on promotion, while Mr. P. St. Mathew Daniel, Registrar of the Divisional Court, Lagos, who entered service in 22nd July, 1903, and whose name appeared in the "Eko Akete" of last week relieves Mr. Smith at the Magistracy owing to the condition of his health.

We wish Mr. Thomas Bankole Buko many years of usefulness to enjoy a well deserved pension, and to Messrs J. H. Smith and P. St. Mathew Daniel good luck in their new sphere of works.

### St. Lukes Church.

The dedication ceremony of a new Church at Sapele erected in memory of the late Rt. Rev James Johnson, D.D., will take place on Monday, the 4th June, 1928, at 8 a.m. Bishop I. Oluwole, D.D., performing.

We congratulate all members of Sapele Church for this signal success.

### Banknote Miser's Fate.

WORTH £20,000. BUT DIED IN RAGS.

*The Man who made his fire of Match-Sticks.*

Once a master tailor in the East-end of London, Abraham Treeves died at the age of 87 on a bed of rags in Gawber-Street, Bethnal Green. He was one of the most notorious misers in London. When solicitors opened a safe in his room they found over £1,500 in gold and bank notes, Government stock certificates, and the title deeds of some houses. Probably the old man was worth £20,000. Yet Treeves was too mean even to buy a will form, but, as he lay on his death-bed, told one to whom he was under a great debt of gratitude, "Open the safe and take all that is in it." He went to bed every night at 8 o'clock to save fire and light, and Used candles instead of gas; warmed himself at his landlady's fire;

Saved match-sticks—even picking them off the street—to light his own fire when he had one;

Saved every pin and button, and counted them;
Had no new clothes in the last six years;
Never rode on a 'bus;
Never went to an entertainment;
Went to the free dispensary;

Refused to pay a penny a week as his share of the gas on the landing; and Wanted his landlady to pay half the cost of having the chimney of his room swept.

His landlord and landlady, Mr. and Mrs. Fowler, declared they had never known him give anything away. He would borrow a light or a smoke, and even medicine. "Until he was dying," related Mrs Fowler, "neither of us had been in his rooms for six years. The only person allowed in was a nephew's daughter who came to do work for him. Every Sunday for years past he went to his nephew's for his meals. On these visits he always borrowed tobacco to save buying. Although he had been married twice, he was a great woman-hater, and used to say, 'I can't stand women, I hate them!' In the streets he was a quaint old figure. Children followed him with shouts of "Old Miser," and jeered as he picked up pieces of wood and coal for his fire—At an inquest on Treeves, Dr. Edwin Smith, the coroner, remarked that there was no doubt the old man had been a miser. Death was due to erysipelas following a face injury, the cause of which was unknown, and a verdict of "Accidental death" was returned.—*The News of the Worlds, 15/4/28.*

### On Leave.

Mr. J. B. Aigoro, 2nd Class Clerk, Accounts Office, Nigerian Railway, Zaria, is on one month's leave as from the 14th May 1928.

**Death of Mrs. Mary Amelia Williams**

The death is announced with deep regret of Mrs' Mary Amelia Williams, widow of the late Mr. I. B. Williams of Raymond House, Broad Street, Lagos, on Sunday, the 27th ultimo at 10.30 p.m.

The funeral service which was largely attended took place the following afternoon at Wesleyan Trinity Church, Tinubu, at 4 p.m. To the bereaved family we tender our heartfelt sympathy. *R.I.P.*

OLUŞAKIN.

---

Si Oniwe-irohin " Eko Akete,"

Mo juba o,

Jọwọ ma şai fun mi ni aye diẹ ninn Iwe Irohin rẹ lati sọ gbolohun meji nipa " Irohin lati Ibadan" to o farahan ninu Iwe Irohin ti Satide (May 19) to koja.

Laise iye meji, mo mọ pe enia alawọ dudu ni ẹniti o kọ irohin na, şugbọn are ibi wun ki akọwe irohin na jẹ mo fẹ ki o gba wipe " Ẹiyẹlẹ fi ẹsin rẹ pamọ o nşe ẹlẹya adiẹ ni." Akọwe na sọ pe E. O. Shobayọ Ijẹbu gigun ni ati jubẹ lo ara Ijẹbu-Ode ni. O da bi ẹnipe akọwe yi nsọ isọkusọ to wun sinu Iwe Irohin rẹ ni. E. O. Shobayọ sọ fun awọn olopa ti nwọn mu ni ọjọ kẹwa oşu April (10th April) pe ara Eko (Logesian) ni on, awọn ọpa Aba si kọ sinu iwe ẹsun (charge sheet) bẹ. Mo rope eti akọwe yi ko gbodọ gbọ pe mo fẹ omi şrọn nu, boya lọnọkeji 'bi Kọnyinde ba şẹ ni ilu tirẹ Taiwo ni nwọn nmu di tabi bẹkọ o le jẹ pe bi Agnyin baru ofin akọwe na le fi iya jẹ Kurumọ dipo rẹ; nitori kinni, nitoripe awọn Kurumọ nikan ni nwọn nşẹ iru ohun bẹ. Boya lọnọ miran, o le jẹ pe awọn ọmọ ilu ti akọwe na ki iru ofin rara ni; şugbọn bi o ba le sọ ilu rẹ fun mi o daju pe ngko darukọ meji tabi mẹta ninu awọn ọmọ ilu rẹ ti wọn tilẹ le ma jiya ẹşẹ wọn lọwọlọwọ yi fun.

Ede ti o tun buru julọ ti akọwe yi pe ni ipari itan rẹ niyi, ' Kini şe ti ẹnyin Ijẹbu kakiri ilu to jẹ pe iru ni nyin ẹ ki wọn ninu ọbẹ, eyi ara." Ede yi jẹ ede mọşaşi ati ede aitọ si ilu nla bi I j ẹ b u-O d e. Nipataki, ọbẹ wo ni akọwe na se silẹ ti awọn ara Ijẹbu ko wọn ninu rẹ ri? " Eyi ara," nitoripe ko gbọ pe enia jale ri! Moropc idi asọbade ati sọdun ni akọwe yi joko si. Njẹ ẹnikẹni to ba ti ru ofin ti o ba si sọpe Ijẹbe ni on, o buşe, o ti di ara Ijẹbu-Ode niyẹn? Iru ede wọnyi jẹ ede ibajẹ ati ede ti ko tọ rara laiye isisiyi ti gbogo Iwe Irohin iyoku nkigbe pe ki awa enia dudu parapọ, ki a fi ara wa şe ọkan gẹgẹ bi enia alawọ dudu kanna, ko ma si ede mọşaşi ati isọkusọ bawọnyi " Şẹkiri ni eleyi, Kurumọ ni tọhun, Ẹgba niyẹn," mọ.

Mo dupẹ lọwọ rẹ pupọ fun aye ti o fun mi.

Emi ni tirẹ nitotọ,

FILA.

## EMỌ KẸNKẸ, KAI IGI DA!

Ẹnu ya ni lọpọlọpọ nigbati a gbọ pe Ile jo ni Oke-Arin ni agogo mọkanla ati abọ oru ọjọ Friday, mọjumọ Şatide ọsẹ yi, a gbọ wipe enia mẹjọ ni lojona sinu ile na. Oluwa rere gba wa lọwọ Idagiri Ọganjọ.—Amin.

## KI ỌLỌRUN ŞỌ WA LỌWỌ IKU AIROTẸLẸ.

Anu pupọ lo şe wa nigbati a gbọ nipa iku ọdọmọ-kunrin kan ti a npe ni Ogunşọla, ti o nşe olukọ ni Şukuru Olowogbowo.

A gbọ pe bi ọdọmọ-kunrin yi ti mura tan ni arọ Wednesday, o si bọ sode lati ma lọ si Şukuru bẹni o kọsẹ o si şubu lulẹ, bi ere bi aşaya o si şe bẹ o di ero-ọrun apapandodo.

Ki Oluwa şọ wa lọwọ iku ojiji bayi. Ki Ọlọrun si tu awọn ara ati obi rẹ ninu.

---


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni ".Oşupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le şẹşẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Şango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maşe gbẹhin ki ẹ to ranşẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.


Disinfectant Soap of
Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home— it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap
Tablets
MAGNET SOAP
MAGNET
SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

# JUST ARRIVED.

Glaxo (*large and small*) 7/6 & 4/6
Gripe Water 1/6
Saccharine 1/-, 1/6
Lactogen 2/6
Kalzana 6/-
Anti-Rhumatic Salt 2/6, and 3/6
Rheumatism Pills 1/6
Yaro (*small and large*) 2/3 & 3/3
Dr. Pierce's Pleasant Pellet 1/6
Pile Pills 1/6
Pile Remedy 7/6
" Ointment 2/6
etc., etc., etc.

Dr. De Roos' concentrated Guittae Vitae for general Debility, shaking of the hands and limbs, dimness of sight &c., miraculous curer, largest size £2 2 0.

Vibrona the Ideal Tonic Wine for lovers of good health 7/6. *Postage extra.*

APPLY TO:—

## Iyin Oluwa Medicine Stores

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
22, Agarawu Street,
109, Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

REMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI IṢỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—" WHITE LAGOS ".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

## TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**
No. L2754.
***Always at everybody's service at Tinubu Square.***
For Terms, Apply to:—
A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## *ILE OWO OYINBO*

# JOHN RADCLIFFE

Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aşetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.